# A RẸ IGBERAGA ỌBA SILẸ

**Daniẹli 4:1-37**

**ẸKỌ 421--- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Bi igberaga ba de, nigbana ni itiju de, ṣugbọn ọgbọ́n wà pẹlu onirẹlẹ" (Owe 11:2).**

**Iṣẹgun**

Diẹ ninu awọn itan otitọ ti o wunilori ju lọ ninu awọn akọsilẹ gbogbo wà ninu iwe Wolii Daniẹli. Ori kẹrin iwe naa ni ẹ̀kọ́ wa oni, Ọba Nebukadnessari, alagbara ti o n ṣakoso gbogbo ayé ni akoko naa ni o sọ gbogbo ọ̀rọ ti o wà ninu ori kẹrin yii.

Nigba ti Nabopolassari, baba Nebukadnessari jẹ ọba Babiloni, Nebukadnessari ti mu awọn ọmọ-ogun rẹ̀ lọ si ori oke ti o jinna ju ọgọrun mile lọ, la afonifoji ati aṣalẹ já, lati mu ikogun bọ̀ lati awọn orilẹ-ede ti o jinna réré ni iha iwọ-oorun Babiloni. Ninu irin-ajo rẹ̀ o ṣẹgun awọn ọmọ-ogun Egipti ti wọn ti lọ si ariwa lati gbogun ti Assiria. Lẹyin iṣẹgun yii, Nebukadnessari yipada si iha guusu o si ṣẹgun Siria, Tire ati Palẹstini.

Nebukadnessari kó ohun gbogbo ti o fẹ́ lati inu iṣura nlá nlà awọn orilẹ-ede wọnyii, o si kó awọn ti o lagbara ti o si jafafa ju lọ ninu awọn eniyan wọn lẹru wá si ilu rẹ̀ ni Babiloni.

**Awọn Ohun ti Eṣu N Beere**

Nebukadnessari beere pe ki awọn ọba ilẹ ti o ṣẹgun wọnyii maa fi iye wura, fadaka, tabi ẹrù ohun-ini kan ranṣẹ si oun ni ọdọọdun gẹgẹ bi owo-ode. O fi diẹ ninu awọn ọmọ-ogun rẹ̀ sibẹ lati ri i pe wọn n fi owo-ode ti oun n beere yii ranṣẹ. Wo o bi iwa yii ṣe jọ ọna ti eṣu n gbà kó awọn ọkunrin ati awọn obinrin lẹru ni ayé yii! Nigba miiran a kó awọn ti o lagbara ti o si jafafa ju lọ ninu awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbinrin a si mu wọn wá si ijọba ti rẹ̀, nibi ti wọn yoo gbé maa ṣiṣẹ fun un. Yoo fi diẹ ninu awọn aṣoju rẹ̀ si ayika lati ri pe wọn n ṣe iṣẹ ibi nigba gbogbo wọn si n mu iṣẹ rẹ̀ tẹ̀ siwaju.

**Ikogun**

Nebukadnessari ti lọ jinna si guusu titi de Egipti nibi ti o ti gbọ́ pe baba oun ti kú, nitori naa o yara pada lọ si Babiloni o si gori itẹ gẹgẹ bi ọba gbogbo ijọba Babiloni. Ilẹ ọgbin ijọba yii wà laaarin odo Eufrate ati odo Tigri. Awọn agbẹ, awọn ọmọle, ati awọn ẹlẹkọ́ ijinlẹ wà ninu awọn eniyan ilẹ naa.

Nebukadnessari lo awọn ikogun lati fi sọ Babiloni di alagbara ati lati mu un dara. O ṣe ọna-omi, ibi ipamọ omi, ebute fun ọkọ-oju omi, ati ilu nla. Nebukadnessari kọ́ awọn ọgba ti o so rọ̀ si ofurufu, eyi ti i ṣe ninu awọn ohun iyanu meje ti ayé igba ni fun iyawo rẹ̀ arẹwa ẹni ti ile rẹ̀ ti wà tẹlẹ ni ilẹ Mẹdia, ilẹ ti o kun fun oke giga-giga.

Awọn ọgba yii jẹ́ eyi ti a kọ́ bi àtẹ̀gùn ti a si gbin itanna, ewebẹ ati igi si. Ẹrọ afami ni a fi n fa omi lati inu odo Eufrate lati fi maa bomi rin awọn ọgba wọnyii.

**Ọlọrun awọn Heberu**

Nigba ti Nebukadnessari ati awọn ọmọ-ogun rẹ̀ ti gbogun ti orilẹ-ede kekere ti Judea ni iha guusu Palẹstini, wọn kó awọn nnkan lati inu Tẹmpili daradara ti Sọlomọni ti kọ́. O mu ninu awọn ohun-elo wura ti a ti yà si mimọ́ fun isin Ọlọrun o si fi wọn sinu tẹmpili oriṣa rẹ̀ ni Babiloni. O mu ninu awọn aṣayan eniyan lati fi ṣe iranṣẹ. Laaarin awọn wọnyii ni Daniẹli ati awọn ọrẹ rẹ̀ mẹta wà.

Awọn ọdọmọkunrin wọnyii yara lati mọ ẹkọ, ati fun ọdún mẹta Nebukadnessari ṣeto fun wọn lati kọ́ ọgbọn ati imọ ijinlẹ Babiloni ki wọn ba le ṣe iranlọwọ ninu ijọba rẹ̀. Bi wọn ti n sin ọba ti wọn si ṣe oloootọ ati olododo ninu ohun gbogbo ti wọn ṣe, Nebukadnessari ni anfaani lati mọ̀ nipa Ọlọrun ti awọn Heberu wọnyii n sin.

Bi ẹyin ti i ṣe Onigbagbọ ba ṣe oloootọ ati ẹni diduroṣinṣin ni ile-ẹkọ ati laaarin awọn olubaṣire yin, awọn kan ninu wọn yoo wá mọ̀ nipa Ọlọrun ti ẹyin n sin, a si le jere wọn fun Oluwa.

**Igberaga**

Nigba ti Danięli sọ itumọ ala Nebukiadnessari nipa ere wura ni fun un, Danięli sọ fun ọba yii pe Ọlọrun ni o fi ala yii ati itumọ rẹ̀ hàn. Nebukadnessari si ti jẹwọ Ọlọrun o si ti bu ọla fun Un. Lẹyin eyi nigba ti awọn ọrẹ Danięli mẹta wà ninu iná ileru, Nebukadnessari ti ri Jesu, Ọmọ Ọlọrun, ti n rin pẹlu wọn, o si ti loye nipa Ọlọrun. Sibẹ Nebukadnessari ko fẹ sọ pe Ọlọrun ni o fun oun ni ipo ti oun wà gẹgẹ bi ọba Babiloni. O fẹrẹ jẹ pe olukuluku eniyan ti ki i ṣe Onigbagbọ́ ni o n fẹ lati fi iyin tabi ọla fun ara rẹ̀ ju eyi ti o n fi fun Ọlọrun lọ. Iru eniyan bẹẹ a maa lọ kaakiri, bi Nebukadnessari ti ṣe, a si maa sọ tabi ki o maa ro o bayii: "Wo nnkan ti emi ṣe!"

**Irẹlẹ**

Nebukadnessari mọ̀ pe Ọlọrun kò fẹ ki eniyan gberaga, ati pe O lagbara lati rẹ awọn ti o ni ero giga nipa ara wọn silẹ. Ọlọrun ni oluṣe ohun gbogbo, Oun ki i si i gbà, eyi nì ni pe O lodi si awọn ti n fẹ iyin tabi ọla fun ara wọn lori ohun ti Ọlọrun tikara Rẹ̀ ran wọn lọwọ lati ṣe tabi ti O ṣe fun wọn; ṣugbọn O n fi oore-ọfẹ -- oore-ọfẹ igbala – fun olukuluku ẹni ti o ba rẹ ara rẹ̀ silẹ (1 Peteru 5:5).

Ọlọrun n fẹ ki olukuluku eniyan ni gbogbo ayé ki o ri igbala, ṣugbọn Oun ko le gba ẹnikẹni ti ko ba le rẹ ara rẹ̀ silẹ là. Nigba ti eniyan ba jẹ ẹni giga ni oju ara rẹ̀ ti o si n rò pe oun le ṣe aṣeyọri ninu ayé lai si iranlọwọ Ọlọrun, Ọlọrun kò le ran an lọwọ. Iru ẹni bẹẹ yàn lati ṣe eto igbesi-aye rẹ̀ to bẹẹ ti ko fi si àye fun Ọlọrun. Ko si aye fun Un lati ṣe iranlọwọ.

**Imoore**

Bi o ba n wà ni ipo ti o dara ni ile-ẹkọ, tabi a n san owo fun ọ ti o le fi ra aṣọ ati ohun ti o ṣe alai ni nipa tita iwe iroyin, nipa ṣiṣe itọju ọmọde tabi nipa ṣiṣa eso fun tita ni akoko eso, nitori Ọlọrun fun ọ ni èro ati ilera ati agbara lati ṣe nnkan wọnyii ni.

Bi o ba n ranti ni owurọ, ni ọsán ati aṣaalẹ lati dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ounjẹ ti O pese, fun ile rẹ daradara, fun aṣọ ti o ni, fun aabo Rẹ̀ lori rẹ bi o ti n lọ ti o si n bọ̀ lati ile-ẹkọ ati ibi iṣẹ rẹ, èṣu ki yoo ri àye to bẹẹ lati mu ọ gberaga.

**Alá**

Ọlọrun mú ki Nebukadnessari lá àlá nipa igi nla kan ti o tobi to bẹẹ ti a le ri i ni gbogbo ayé. Igi yii so eso ti o tó lati fi onjẹ fun gbogbo eniyan ti o wà ninu ayé, awọn ẹka ati ewe rẹ̀ si jẹ́ aabo fun gbogbo ẹyẹ, ẹranko, ati gbogbo eniyan. Ninu ala rẹ̀ ọba ri ẹni ti a n pè ni "oluṣọ," ẹni ti a gbagbọ pe o ni lati jẹ́ angẹli kan ti a rán lati Ọrun, ti o n wi pe ki a gé igi naa lulẹ ki a si fọn eso rẹ̀ ká, ki awọn ẹyẹ ati awọn ẹranko igbẹ ti wọn ti n gbadun eso rẹ ati iboji rẹ̀ ki o jade kuro labẹ rẹ̀. A ko gbọdọ fa a tu kuro, ṣugbọn ki a fi gbongbo rẹ̀ silẹ ninu koriko tutu igbẹ nibi ti iri Ọrun yoo mu ki o wà laaye. Eyi ni a o ṣe ki awọn eniyan ba le mọ̀ pe Ọlọrun ni alakoso ayé, Oun ni o si n fi àyè silẹ fun awọn ọba, awọn baalẹ awọn olori, lati wà ni ipo wọn.

**Itumọ Rẹ̀**

Nigba ti awọn ọlọgbọn iyoku ninu agbala Nebukadnessari kò le sọ itumọ ala yii fun un, Danięli wá. Nigba ti a sọ àlá yii fun un, iro-inu rẹ̀ daamu rẹ̀. Fun igba pipẹ kọ sọ ohunkohun. Iroyin buburu ni fun ọba. Njẹ Danięli ha le sọ otitọ fun un bi? Bẹẹ ni, Danięli jẹ́ oloootọ si ẹri ọkàn rẹ̀ gẹgẹ bi iṣe rẹ̀ lati igba ti a kọkọ mu un wá bi ẹru si Babiloni. Danięli sọ fun ọba pe oun ni igi ti o tobi ti o si lagbara, ṣugbọn a o le e jade kuro ninu aafin rẹ̀, ati fun ọdun meje yoo maa gbé gẹgẹ bi ẹranko igbẹ, titi yoo fi mọ̀ pe Ọlọrun ni o gbé e ga, Ọlọrun ni o tun rẹ̀ ẹ silẹ.

Otitọ nì pe a fi gbongbo igi naa silẹ ninu ilẹ jẹ́ apẹẹrẹ pe ijọba Nebukadnessari yoo tun pada jẹ ti rẹ̀ lẹyin ọdun meje, nigba ti o ba gbà pe Ọlọrun ni Alakoso ninu ijọba eniyan.

**Ainaani Ikilọ**

Daniẹli rọ Nebukadnessari lati ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ki o si ṣe rere ki Ọlọrun ba le dariji i. Ọlọrun fun un ni àfo ọdun kan lati gbadura, ati pe ki o si rẹ ara rẹ̀ silẹ ṣugbọn ọba kò gbadura.

Ni ọjọ kan bi Nebukadnessari ti n rin ninu aafin rẹ̀ ti o si wo ilu nla Babiloni, ti oun si gbagbe Ọlọrun, o yọ̀ ninu ohun wọnni ti o ti ṣe. O fi igberaga wi pe, "Koṣepe eyi ni Babeli nla, ti emi ti fi lile agbara mi kọ́ ni ile ijọba, ati fun ogo ọlanla mi?" Bi o ti n sọrọ lọwọ, idajọ nì, nipasẹ eyi ti a ti kilọ fun un bẹrẹsi i ṣẹ. A lé ọba jade kuro ninu aafin rẹ̀ daradara gẹgẹ bi Daniẹli ti kilọ pe a o ṣe si i bi kò ba ronupiwada. O wá n gbé ninu papa-oko, o si n jẹ koriko bi maluu ti i jẹ, irun ara rẹ̀ si hù jade titi o fi dabi iyẹ idi, eekanna rẹ̀ si gùn bi ti ẹyẹ.

**A Mu Un Pada**

Ṣugbọn gẹgẹ bi ala nì ti sọtẹlẹ, lẹyin ọdun meje òye Nebukadnessari si pada bọ si ipò, a si tun bu ọla fun un gẹgẹ bi ọba lẹẹkan si i. Njẹ o mọ idi rẹ̀ ti Ọlọrun fi dá òye rere pada fun Nebukadnessari ti o si gbe e ga gẹgẹ bi ọba lẹẹkan si i? Idi rẹ̀ ni pe ni ikẹyin Nebukadnessari fi ogo ati ọla fun Ọlọrun o si mura tán lati jẹwọ pe Ọlọrun ni Alakoso ayé, Ọlọrun ni O si n gbé awọn eniyan soke ti O si tun n rẹ̀ wọn silẹ.

**Ẹri**

Nebukadnessari kọwe si gbogbo eniyan ayé lati sọ fun wọn bi Ọlọrun Ọrun ti rẹ oun silẹ nigba ti oun gberaga. Ọrọ Nebukadnessari jẹ́ ẹri si iṣeun Ọlọrun, ohun iyanu ti Ọlọrun ti fi hàn fun ọba, ati ẹ̀tọ́ ati agbara Ọlọrun lati jẹ́ Ọba ayé. O dabi ẹri ti iwọ le jẹ́ ninu ile isin nipa iṣeun Ọlọrun ti o mu ọ wá si ironupiwada ti iwọ fi mọ ailera rẹ; ati ẹ̀tọ́ Ọlọrun lati ṣakoso, ati lati jọba ninu ọkàn ati ayé rẹ.

**Aidaju Igbesi-ayé**

Iwọ ha rò pe o wà labẹ aabo ninu igba ọ̀dọ rẹ ati ninu agbara rẹ? Bi iwọ kò ba i ti ri igbala, Ọlọrun n pè ọ lati ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ ki o si ri igbala. Awọn anfaani itura ati ohun meremere ti o yi ọ ká le yipada ni ọjọ kan nipa iṣẹlẹ ti a kò rò tẹlẹ bi pe ki ọkọ̀ kan fún ara rẹ mọlẹ ninu agbako ọkọ nla tabi nipa pe ki alejo ti a kò reti tẹlẹ bi Ikú mú baba tabi iya rẹ lọ si Ọrun. Njẹ iwọ yoo ha le gbadura nigba naa pẹlu igboya, tabi iwọ yoo ha ni lati kọkọ ronupiwada ẹ̀ṣẹ ati igberaga ọkàn rẹ ki Ọlọrun to le gbọ́ adura rẹ?

## AWỌN IBEERE

1 Njẹ o le darukọ diẹ ninu awọn orilẹ-ède ti Nebukadnessari ṣẹgun?

2 Ki ni diẹ ninu awọn ilọsiwaju ti Nebukadnessari ṣe ni orilẹ-ède ti rẹ̀ pẹlu ikogun?

3 Lati orilẹ-ède wo ni a ti mú Daniẹli lẹru wá?

4 Ta ni Ọlọrun kọjujasi? Ta ni O si n fi oore-ọfẹ fún?

5 Ki ni ṣe ti o ṣe pataki fun wa lati fi imoore hàn si Ọlọrun fun awọn nnkan ti o n ṣe fun wa?

6 Njẹ itumọ àlá naa ti Daniẹli sọ ri bẹẹ bi?

7 Bawo ni Nebukadnessari i ba ṣe yẹra fun idajọ ti Ọlọrun fi hàn án pe o n bọ̀ wa?

8 Bawo ni ẹni kan ninu wa ṣe le yẹra fun idajọ Ọlọrun lori igberaga?